**Owe**

Adię iba l'ękọ, iba l'atan se nkan. Imado iba se bi ękęlę a ba'lo je. Ęru iba f'oba, enia ko ba ti ku ękan.

# ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ

**Asoje**

Enia ma jeki t'enia sunwon, t'eni ma sunwon ko ni gbo. Apa omode ko le ka igi Ose, yio ma doyika.

VOL. XIII No 685 LAGOS. SATURDAY FEBRUARY 18, — FEBRUARY 24, 1961. KỌBỌ MEJI (2D)

# OKU LUMUMBA ARIWO, AAYE LUMUMBA IJONGBON.

ROGBODIYAN ati ija igboro ti bẹ silẹ kakiri agbaiye, paapa ni agbegbe awa enia dudu nisisiyi, lori edekoyede kan ti o ti bẹsilẹ larin awọn Olotu ijọba ilu Kongo. Ijongbọn na bẹrẹ larin Ọgbẹni Kasavubu ati Lumumba ti nwọn njẹ oye Alakoso ijọba ati Olotu ijọba.

Nigbati aye ipo wọn na se awọn mejeji bi igbati ọti npa enia, ni Ọgbẹni Kasavubu sọ wipe on yọ Lumumba kuro laye Olotu ijọba ilẹ Kongo, Ọgbẹni Lumumba na sọ wipe on na yọ Kasavubu kuro laye Alakoso ijọba, ori yi ni o da ilu wọn si meji ti enikini ni awọn alatilẹhin rẹ, bakanna ni enikeji ni tirẹ. Awọn mejeji wa gb'ogun ti ara wọn.

Ọtẹ na ni nwọn nṣe titi ti ọwọ wọn fi tẹ Lumumba ni gbati wọn parapọ le on ni kan lori, Ọgbẹni Kasavubu ti o jẹ Alakoso (President) fa Mobutu olori ọmọ ogun mọra, ati ọta orun kogbẹbọ enia fun Lumumba ti nwọn npe orukọ rẹ ni Tshombe ti o wa nilu Katanga.

Irohin ti a tun gbọ lẹhinti nwọn ti mu Lumumba s'ẹwọn tan, ni gbigbe ti a gbe kuro ni Elizabethville lọ si ọgba ẹwọn Kantanga, afi iku rẹ ti a tun gbọ. Eyi l'o mu awọn ọmọ ilẹ Nigeria, awọn akẹkọ, oṣiṣẹ ati akọwe to pẹlu Pos ti nwọn fi aṣọ dudu bo lara lọ sile Aṣoju ilẹ Belgium ki rogbodiyan ija to fẹ bẹ silẹ.

Nwọn fi oko fọ ọpọlọpọ jigi Ferese ṣọbu awọn Oyinbo l'Ẹhingbeti, ati ile Aṣoju ilẹ America ni nwọn ba ẹ pupọ nwọn tilẹ ṣe awọn Oyinbo le e pelu moto wọn, gbigbe ni a gbọ pe nwọn gbe Oyinbo kan lọ si ile iwosan Creek Hospital.

Bi agan ti mbẹ lori iku Lumumba niẹ Nigeria bẹnani o mbẹ kakiri agbaiye, a gbọ pe Ọlọpa mu Ọgbẹni Olabisi Aja'u nilẹ Rangoon lẹhinti oju oku'a si e Aṣoju Belgium ati ti Amerika fun ẹdun iku Lumumba.

## Gomina Agba Yin Oga'gun Ile Nigeria

Zaria— Ninu irin abẹwo Ariwa, ilẹ Oke-Oya ti ọlọla nla Dokita Nnamdi Azikiwe Gomina Gbogbo-gbo ilẹ Nigeria, nigbati o lọ bẹ ile iṣẹ awọn ọmọ ogun wo nilu Kaduna ati Zaria, ni o ṣe aponle Ọgagun Major General Foster ati awọn alabaṣiṣẹ pọ rẹ fun ọgbọn ati la aye ti nwọn fi nṣe atọna awọn ọmọ ogun ilẹ Nigeria daradara.



Gomina Gbogbo-gbo ... Ọga'gun Major-General Foster lati ilu Zaria wipe on kun fun ayọ nigbati o bẹ ile iṣẹ awọn ọmọ ogun wo nilẹ Ariwa.

Ẹnu ko irohin iyesi ti nwọn nṣe fun Ọlọla nla Dokita Nnamdi Azikiwe, Gomina Gbogbo-gbo ilẹ Nigeria ati Ọlọla Omidan iyawo rẹ ni Ariwa, nilẹ Oke-Ọya.

## Afape De Fila Oye, Adupe.

Lati agogo Mejila ni ọjọ Sunday (12/2/61) ni ẹsẹ ko gbeji ni orere Iga Olu a titi lẹ de Iga Olumẹgbọn, Iga-Idu ngaoran Ẹnn-Ọwa, oju 'gi-Ito fun awọn ... rota, alabaie, mogbomowa ti nwọn wa wo ai de fila fu Abdul Rashidi Afape Akibe, Oloye Oluwa titun.

Oloye Olumẹgbọn ni o de fila fun u, ni dede agogo merin-abọ ninu Iga Olumẹgbọn, lẹhinna ni a mu Oloye titun na lọ kanse gẹgẹbi asa ibilẹ kakiri gbogbo ibi ti o tọ t'oye, ki nwọn to dari lọ fi a'ọ fun Ọba Adele Keji ninu Iga Idunganran.

Orisirisi ilu lo wa nibẹ, ti nwọn si nkọ orisirisi orin ṣugbọn orin ti gbogbo enia tẹn mọju, ti nwọn si ngbe ni,

"Iwe t'ẹkọ tẹsun t'ẹwo owọ wa lo bọ si"

Gbogbo awọn Balẹ mẹrẹrin, Apapa, ati Isongbe wọn ati awọn Ijọ, Ṣẹkiri ati Orisirisi awọn enia ti o gba ilẹ ni Apapa ni wọn wa juba fun Oloye Titun yi.

Bi a ba ni ki a ma a kọ irohin yi lọ, gbogbo iwe wa l'oma kun Oloye Oluwa, awa bẹrẹ fun oji o.

Fila Apẹ ori, Bata Apọlẹsẹ, ẹmi gigun ti anfani o. Amin.

# EKO AWON ENIA WA PADA

Calabar – Oloye Obafemi Awolowo ni o to waju range si Olori... ba awon ... so wipe ki awon k... awon omo ogun ati awon olopa ... Nigeria pada wale.

... Lehin ... ikede iku Ogberi Lumumba ti jade ... Oloye Awolowo ... n aj... re nile Ila-Crun, nilu Calabar, nibe ni o ti te waju ra... se.



Oloye Awolowo so wipe ko dara ki ... ri ... omo ogun Nigeria ... ma lo fun atilehin awon ti o ... ijoba enia dudu ... ko ba okan wa mu, wipe ki Nigeria se atilehin fun atije ijoba enia dudu ... se ehin.

Oloye Awolowo so wipe awon ... Kasavubu, Mobutu ati Tshombe je asoju fun ile ajeji ati pe egbe ... Majemu ... (U. N O.) gba lati jeki nwon ... ijoba subu, ... nwon ti faramo ... Olotu ijoba ti o ... eto.

N... igbati ... Majemu ... ti gbowe ki nwon pa Lumumba ... wipe awon ... ajeji tilo won ati Kasavubu, Mobutu ati Tshombe ... iru ise lati le ... ti awon ba le ... Kongo.

## Ina Nla S'ode Kanrin!

KANO: ... ti jo ise oja ... yi.

Ofote gba awon P... ti ... kan abo ki awon ... bajoto ... (£5,000), ... kori mo ohun tio fa ... na.

# Owo Ko Se Fi Sere

Lati owo Prince Adelakun

Inu mi yio dun ti Olotu Iwe irohin Eleti-Ofe bale ... laye lati so itan ... fun awon ... gbogbo.

Ngo koko pa itan na ni alo ni ki nto wa so o ni itan Alo o. Alo. Kini nkan meta to pa nkan mejila, ... meta si ... nkan mejila, nkan mejila pa nkan meta ... Nkan mejila ... wa di egbe.

(Wo yoku loju ewe keje)

# Oba Obinrin Lo Sibi Apeje Nla Nile Inda

PAKISTAN – Ni ale ojo ti Alaye luwa Oba Obinrin ati oko re Omoba Philip de silu Pakistan, ni nwon lo sibi apeje nla repete ti Alakoso (President) ilu Pakistan se fi bu ola fun awon olola nla na ni Karachi.



... ikan lati idi oko ofurufu ti awon ... na ti wo mole titi de arin ilu, nwon si ti fon ododo oloorun didun si gbogbo oju-ona.

Advt 20.

## Federation Of Nigeria Second Development Loan

The Central Bank of Nigeria have been authorised by the Federal Minister of Finance to raise in Nigeria a Federal Government loan of £10,000,000.

The Stocks to be issued will be :-

£2,000,000 5 o/o FEDERATION OF NIGERIA SECOND DEVELOPMENT STOCK 1967.
£4,000,000 5 1/2 o/o FEDERATION OF NIGERIA SECOND DEVELOPMENT STOCK 1977.
£4,000,000 6 o/o FEDERATION OF NIGERIA SECOND DEVELOPMENT STOCK 1985.

Interest, which will be paid half-yearly on the 22nd September and 22nd March, will accrue at the rates shown above and repayment will be made as follows :-

5 o/o Federation of Nigeria Second Development Stock, 1967 - on 22nd March, 1967.
5 1/2 o/o Federation of Nigeria Second Development Stock, 1977 - on 22nd March, 1977.
6 o/o Federation of Nigeria Second Development Stock, 1985 - on 22nd March, 1985.

Application lists for the loan will open on the 22nd FEBRUARY and close on 22nd MARCH, both dates inclusive. Applications must be in multiples of £10 and can be made only on the special forms available at banks throughout the country. Application for different stocks must be made on the different application forms provided.

The stocks will be issued at par and payment in full must be made with applications ( i. e, £10 must be paid for every £10 of stock applied for ). Receipts will be issued for payments and will later be exchanged for Stock Certificates. If desired, payment may be made by means of a draft on a United Kingdom bank but payment in this way may be made only to the Central Bank of Nigeria direct, accompanied by the relative application form.

Notification of allotment will be made direct to subscribers by the Central Bank of Nigeria as soon as possible after the 22nd March and stockholders will be advised at the same time when to collect their Stock. Certificates from the Banks where they subbmitted Lagos, their applications.

Pending the operation of a Stock Exchange in prospective buyers and sellers of the stocks should, after allotment has been made, approach their own bankers who will get in touch with the Central Bank with a view to affecting a market.

Further information can be obtained from the Prospectuses available at banks on and after 22nd February.

**R. K. C. Giddings,**
GENERAL MANAGER.

Central Bank of Nigeria,
Tinubu Square,
Lagos.
February, 1961.

E MA KA'WE IROHIN
ELETI-OFE L'OSOSE

## Awon Esin Meji Jo Ku

BORNU– Ni ọjọ ti awọn nkọla fun ọmọ ekee kan nilu Karari, abule kan nilẹ Bornu, ni awọn ọpọ enia gun ẹṣin ti nwọn fi njo ilu ilẹ wọn gẹgẹbi aṣa iṣẹdalẹ ilu na.

Awọn ẹṣin meji kan jo titi, nwọn kọlu arawọn ibẹ ni awọn mejeji ku si, ṣugbọn awọn enia ti o gun ori awọn ẹṣin na fi njo ni nwon fi ara ṣe ese pupọ, nwọn si ko wọn lọ si ile iwosan.

## Ilu Agadir Mi Titi !

A gbọ irohin wipe iṣẹlẹ kan ṣẹlẹ nilu Agadir (un bi iṣẹju kan ti iro abẹ ilẹ mi ilu titi ni ọjọ Satide kan, ni dede asiko ti iṣẹlẹ nla kan ṣẹrẹ ba ilu na jẹ niwọn ọdun kan sẹhin.

Sugbọn adupẹ wipe enia ko ku sinu eyi, bẹni ko si ba ile jẹ pupọ.

## OLOPA MU ENIA META

KANO – Awọn enia mẹta ni ọwọ ọlọpa tẹ ti nwọn ti daduro si itimọle lori ole ti o ja ninu ile Iṣura ile ifiweranṣẹ ( Posts & Telegraphs ) ni oru ọjọ ọsẹ ti o kọja nibiti nwọn ti ji owo ti o le ni ẹgbẹta-din-logbọn ( £5,443,11/-). pọnun

Ọga ọlọpa-inu sọ fun oniwe irohin nilu Kano wipe awọn ni igbagbọ pe enia marun ni awọn ole na, awọn si ni ireti wipe laipe ọwọ yio tẹ awọn meji yoku ti o ṣi nra fanda kiri.

Oniṣẹ alẹ (Watchman) ti o nṣọ ile ifiweranṣẹ na ti nwọn kọkọ mu mbẹ ni itimọlẹ bi awọn ẹlẹri ti nṣe iwadi siwaju lọwọ.

## Onile Ita Onje Ilu Kano Jare Ejo Re

Kano– Iyafin Paulina Ashilonu ti o nṣe iṣẹ Ile-ita-onjẹ (Hotel) ni ilu Kano ni adajọ Kotu da lare ẹjọ ti o pe OmidanVictoria Agana.

Iyafin Paulina pe ẹjọ fun owo gọbọyi lati gba igba pọnun fun orukọ rẹ ti Agana bajẹ. O sọ wipe Omidan Agana pe on ni ole ati ajẹ, wipe gbogbo ohun alumọni ti on ni, ajẹ on ni on fi npa awọn enia dudu ati enia funfun ti on nko ẹru wọn.

Adajọ da lare, wipe ki Omidan Agana lọ san pọnun mẹrin-din-logoji ati ṣile mẹwa (£36 10/-) fun u.

# ELETI--OFE

ANJUWON KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

5, Koroko Street, Lagos. "ELETI OFE, LAGOS"

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. XIII. No. 685. SATURDAY FEB 18, FEB 24, 1961


# OLOTU IJOBA APAPOSE LODI SI IKU LUMUMBA

EKO - Alhaji Sir Abubakar Tafawa Balewa, Olotu ijoba ile Nigeria te Waya ranse si Ogbeni Dag Hammarskjoeld, Akowe Agba Igbimo Majeobaje wipe ijoba ati awon enia ile Nigeria lodi gidigidi si irohin iku Ogbeni Patrice Lumumba, Olotu ijoba ako o tile Kongo.



"Mo ti gbo pelu owariri ati ibanuje irohin buruku nipa iku Ogbeni Lumumba. L'oruko ijoba ati awon enia ile Nigeria, mo fe so wipe awa lodi gidigidi si ona irufe eyi ti buruku yi fi sele".

Awa enia ile Nigeria ni igbagbo si ipari edekoyede larin awon Oselu, ako si le gba wipe ki a fi owo lile tabi owo ina mu enia ni o le mu ki ija na pari darandara.

Awa lodi rapo si iwa ipania ni ipakupa ti o tati ko iselu ti egbe kan nile Kongo, eyiti yio ja gbogbo wahala igbimo Majeobaje lati pari oro na kule, tabi ti ko ni jeki awon gba ipari edekoyede na.

## TALO PA LUMUMBA ?

Ogbeni Patrice Lumumba ni eniti a gbo wipe awon enia ile Kongo dibo yan si ipo Olotu ijoba won, nigbati awon gba Ominira kuro labe ijoba Belgium. On si ni a gbo wipe awon ti pa ni ipa oro nisisiyi.

Nisisiyi, boya awon ti Lumumba je idena fun nile Kongo yio lero wipe nigbati Lumumba ti ku, ki awon ma dara ti o ba wu awon nile Kongo l'oku. Sugbon arawon ni awon ntan je, bi won ba ni irufe ero bayi, nitoripe iku Lumumba ko le da ise ilosiwaju ile Kongo duro. Airoju ati airaye sese bere ni, gegebi a ti nwo oye ilu na si Nkan le daru, ki o to toro.

Lotito ni awon omo ogun igbimo Majeobaje (U. N. O) se idabobo Lumumba lowo omo ogun Mobutu, sugbon nigbati awon mu ti nwon si ju s'ewon lai gbo t'enu re, igbimo Majeobaje ko tile so gbolohun kan si.

Igbimo Majeobaje ni agbara lati gba Lumumba sile nigbati nwon mu sugbon nwon ko se be. Nwon fi ewon de, nwon nje niya, awon osise igbimo Majeobaje so wipe oro ile awon Kongo ni, ki ise ohun ti awon le da si.

Enyin enia wa, e s'akiyesi ara.

## Ijoba Ti Ile Ise Ligali

EKO - Ijoba Apapose ti ile Nigeria ti ile ise ti awon npe ni "Ligali Commercial Syndicate" ti o nfi owo ti o le ni egberun (£1000) ponun sise.

Ofin ile ise na ti ijoba ti jade ninu iwe ikede ijoba ti awon sese te jade.

Alakoso ile ise na ni Ogbeni Abdul Raheem Ligali ti on ni ile 59 Opopo Ojo Giwa, l'Eko, ti o nse owo lowo fun ere ole jija ati mopanpa jale.

Ofin ile Nigeria fun awon ile ise egbe (Company) ni wipe eyiti ko ba se dede nipa ki o ma n l'ilan Kota atabi ise ba ti nlo tabi ipade egbe ile ise na ti awon ba je, bi ile ise na ko ba bere ise titi odun kan ti n-ce ti ko jo tabi ti o ba da ise duro fun odun kan ijoba nilati da duro, ki awon ti ile se -a.

## Nwon Fe Ti Kotu, Adajo Nsokun

OTURKPO - Agbo rere ir hin kan ti a gbo lati ilu Oturkpo ni wipe, awon ig imo Alase ijoba ibile se asare, nwon si pinnu lati ti gbogbo kotu ibile ti o wa ni agbegbe won, won yio si si ile ejo mefa ti yio je ti adajo ti o mo ofin lati ma sise ni gbogbo agbegbe na.

(Wo yoku loju ewe keje)

DA EHIN-DIDUN RE DURO

nipa titete mojuto awon eree inu ati apo-ito re

LO

DeWitt's
Kidney & Bladder Pills

Ki o si bo lowo awon irora ti e nko e sinu arun

LAKUREGBE,
ARA-RIRO, EHIN-DIDUN
ati, Awon IYONU APO-ITO



DeWitt's
Kidney & Bladder Pills

L'arin wakati die ni wa a ti fi ayorisi ise re


## Ebun Fun Gomina Ipinle Iwo-orun

OGBOMOSO – Ninu irin abewo re si awon ilu ipinle Iwo-orun, Gomina, Sir Adesoji Aderemi lo bi awon igbimo ibile ilu Ogbomoso soro.

Iyawo Alaga igbimo, Ogbeni Victor Olajide, ni o gbe ebun ti ilu Ogbomoso fi ta Olola Gomina na lore le lowo.

---

## E Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe Ti O Kun Fun Irohin Aladun

---

## Ijoba Fe Si Ilewe Afoju Fun Awon Omode

EKO – A gbo wipe ijoba apapose yio si ilewe fun awon afoju omo ekee si Surulere.

Ilewe na yio je ibugbe fun awon omo akeko ati pe ofe ni eko ibe yio je fun awon omo ekee bi olodun marun si mesan.

Ijoba kesi awon obi omo ti o ba je afoju ki o fi oruko ati ojo ibi omo na ranse si ile ise eko iwe ( Ministry of Education, ) nilu Eko.

Awon oluko ti nwon ti ko ni eko pataki fun awon afoju omo ni nwon yio gba sibe.

---

## Igbimo Oja Yio Se Atunse Owo Koko

IKEJA - Ki Alaga titun fun igbimo oja to woko Ofurufu ni Ikeja lo silu Remu ni o so wipe gegebi o ti je owo oja Koko r'ehin ni'is'yi, igbimo on yio wa ona ti owo Koko yio fi gbera soke fun awon agbe ti nkan na kan lara daradara.

Alaga Oloye F. O. Awosika so wipe koko ni egun ehin ipinle Iwo-orun, on yio si wa orisirisi ona ti owo re yio fi san fun awon agbe ju bi o ti wa nisisiyi lo. O so wipe awon sese bere si wahala ki koko le lowo lori ni.

Oloye Awosika fi ope fun Ijoba Iwo-orun fun aye ti awon fi on si lati le se ise fun ilu ninu igbimo oja. O si se ileri pe on yio sa gbogbo agbara on lati se ise na ti awon enia ko fi ni ke abamo.

## IYAWO NSOKUN LORI OKU OKO RE

Dijon– Okunrin kan ti o ti lo si ile ise re ni ona jijin ni o pada de ni ojo keji ti o wa ba iyawo ati awon ebi re ti nwon nsokun legbe oku ti nwon te sori ibusun ninu ile re

Awon olopa ni o se alaye oro na, wipe okunrin kan ti o jo George Lequet, ti nwon npe ni Pierre Kohut, ti nwon dabi omo ojo kanna, ti gigun won ri bakanna, ti o wo irufe aso ti George wo ni o se agbako jamba moto ti o ba loju je nitosi ile George ni ale ojo Jimo ni nwon si gbe lo si ile George Lequet.

Eyi ni o jeki George wa ba oku ati awon ebi re ti nwon nsofo re ninu ile re.

Nigbati George de ni ariwo ta, ti awon olopa fi se iwadi ki nwon to mo wipe elomiran ni o ku ki ise George Lequet.

Otito ni oro ti o so wipe mejimeji ni Olorun da awa enia si ile aiye.

# NWON RI EWETABA IGBO LOWO ELEWON

oo—oo—oo

Ijebu-Ode - Ọkunrin kan ti o nse ẹwọn lọwọ ninu ọgba ẹwọn ilu Ijebu-Ode, ni nwọn tun mu wa siwaju adajọ Kotu ibile nilu Ijebu-Ode fun ẹsun wipe nwọn ri ewetaba Igbo (Indian Hemp) ti nwọn di si ọna mẹta lọwọ rẹ ni ọjọ kini oṣu February, 1961.

Ọdaran ẹlẹwọn na, Muraina Ajani, sọ wipe on ko jẹbi ẹsun na, adajọ yẹ gbigbọ ẹjọ na si ọjọ Satide ọjọ meji-din-logun oṣu yi.

Ninu Kotu kanna ni nwọn tun mu agbẹ roko ara Aiyepe, Jimọ Bakare wa siwaju adajọ fun ẹsun wipe eleyini nṣe ọgbin ewetaba Igbo ninu oko rẹ ni Ologbẹn.

Awọn ọlopa sọ wipe nwọn ri to idi ewetaba Igbo marun ninu oko rẹ ni ọjọ kọkan-lelọgbọn oṣu January, 1961. Adajọ fi gbigbọ ẹjọ na si ọjọ keji-din-logun oṣu February, 1961, bakanna.

# AKOSILE TO NIDI

Lati ọwọ J. Awojulugbe

Ẹmi mimọ ti o wa lara awọn enia nwọnyi lati le ni ọgbọn ati ba awọn miran gbe, ẹmi na ni o jẹki a ri ako silẹ nipa ọrọ Jesu Kirisiti loni yi.

Ẹni kọkan ninu awọn ti o kọ'we nwọnyi, kọ gẹgẹ bi o ti fe ati bi o ti ye wọn si ati bi ẹmi ti dari ẹnikọkan si, nitorina ni a ṣe ri itan na ni orisirisi, ṣugbọn iyanu gan ni awọn itan na jẹ, nipa ẹkọ re tabi igbe si aiye rẹ ṣe ẹ mọ pe itan nipa ẹkọ rẹ ni o yatọ, ṣugbọn itan igbesi aiye rẹ ko yatọ rara.

Ninu itan ati iṣẹ ti o jẹ iyanu yi o yẹ ki o jẹ ohun pataki fun wa, o yẹ ki awa na ṣe afarawe awọn ti o ti ṣe iṣe akọsilẹ wọnyi.

Awa ni lati gba Jesu gbọ, ti awa ba ti le gbagbọ pe otitọ ni akọsilẹ nipa ẹkọ ati igbesi aiye rẹ.

Nitorina ẹ jẹki a gbiyanju lati le fi ara han fun Jesu pe awa na gbagbọ, nigbana oye akọsilẹ yi yio si tumi'ma ṣe wa siwaju si.


# OKU'JA WOLU

NIGBATI ỌJA KO BA TA, TI ẸNITI O NRA ỌJA KO TA EYITI O RA, BAWO NI YIO OTI ṢE LE RA OMIRAN. EYI NI GUN TI ONIṢOWO LE ṢE TI ỌJA RẸ YIO FI MA TA BI IṢU AKARA GBIGBBONA

**E polowo ja Yin**

**Sinu Iwe Irohin**

**LETI-OFE**


# Okunrin Agbe Kan W'ewon

ONITSHA - Ọmọkunrin agbẹ roko kan ti iyawo rẹ ti kọ silẹ lọ, ri iyawo na tun pada wa si ile rẹ wa si ile rẹ lati wa sin gbese owo ti arakunrin ọkọ ti o ti kọ silẹ lọ jẹ.

Nigbati iyawo na fẹ pada lọ si ile rẹ, ọkọ ti o ti fi silẹ sọ wipe on yio wa wọn kọja silu Onitsha ki nwọn to lọ wọkọ ti ẹrọ ngbe rin lọ silu wọn. Iyawo ati awọn enia rẹ ti nwọn sin wa gba gbese wa gba gbese owo na si gb'ọjẹgẹ wipe ki o wa wọn sọdọ.

Nigbati ọkọ de arin odo ni ọkọ iyawo yi ọkọ biri, o si sọju de sinu odo, o bẹ le iyawo rẹ lori o si yin lọrun pa. Nwọn ko ri oku obinrin na.

Iṣẹlẹ buruku yi ṣẹlẹ ni ọjọ kẹjọ oṣu October, ọdun to kọja. Adajọ sa konko ẹwọn ọdun mẹwa mọ lara.


BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL!

Fun ina dídá ati fun imọlẹ

BP SUPERLITE

KEROSINE

L'ayo!




Ti o ba ṣepe Kerosine lo fẹ BP Superlite l'ayo o le ri rà nibikibi, ko si wọn, o mó daradara, owun lo si dara ju fun onje-sise, iná-titàn ati lati mã fi yàná Kerosine ti oti dara to BP Superlite

BP ju gbogbo wọn lọ!

# NWON FE TI KOTU, ADAJO NSOKUN

(O ku ti loju ese kerin)

Awon Alaṣe ijoba hilẹ fi tit awon Kotu na si ọjọ kokanlelogbon osu March, odun yi. Nwọn si sọ wipe enikeni ti yio ba ṣiṣe tani ti nwon yio gba si iṣẹ ninu awon ile ẹjọ na yio ni ti ni iwe eri onipo keji (Middle Two Certificate) ki o si jẹ ọmọ ibilẹ Idoma.

Lati igbati ikede yi ti jade ni opolopo iwe ti nwọn nkọ ti nrojọ si ile iṣẹ Alaṣe Kotu ibilẹ (Commissioner of Native Court) tilu Kaduna ati Ajẹ ẹ ti o wa fun agbegbe Benue, wipe ki nwọn mase gba ipinnu ti awọn Alaṣe ijọba ibilẹ ṣe na.

Awọn oṣiṣẹ Kotu ti ekanna kan sọ wipe ipinnu wọn na ko dara fun awọn, nitoripe awọn ni enia pupọ ti awọn nilati tọju.

Ọkan ninu awọn oṣiṣẹ na tilẹ nsokun oju niwaju awọn agbọrandun rẹ gẹgẹbi o ti ro ara rẹ pe on ti dagba rekọja enito le ma a wa iṣẹ miran kiri.

# ORO NIPA ESIN

LATI OWO OLAJIDE BABSON

Mo dupe lowo awon oniwe Eleti Ofe ti o gba mi laye ki ti le sọ iwọn iba oro die fun awa onigbagbo Kiristeni, pataki julọ fun awon Musulumi.

Asiko na ti de tan enyin Musulumi enia ti ẹkọ yo (Iti ie ti o wa loju yin ki won to ma yọ ti ọmọ olomo) "O se bi owe".

O le nkan pataki ti o nma dun mi nigbati mo ba nrin kiri ni ale asiko Awe ti awon Alfa le gbe tabili si Ita ti won ko ni maa ṣe wasu ti Olorun ran won nipa Kikirun dede ati nkan miran ti o ye ti won ki nse lati fi nna han won, kaka bẹ ẹ, won ama ba esin elesin je nipa o se Jesu ko se Jesu.

Kini ohun ti o fa ti o fi le wipe ti Jesu nikan le ri wi tabi Ijọ nikan ni Ojise Olorun ti o wa si aiye ni ? tabi Alfa Muhammadu ninu won ki lose ti e ki nsọrọ nipa yin ? tabi on yin lagbara ju Jesu lo ni ? Mo fe ki e fi ye mi dada.

O di Ijọba mele ti e ri awọn Onigbagbọ ki a ma wasu pe Muhammadu ko nse Ojiṣẹ Olorun ? tabi a so wipe esin Imọle ko tọ suna, kaka bẹ, e nso wipe esin Igbagbọ kirsitẹni ko nṣe esin ti dara. Eyi ọlanla ni.

Okuku san ki Olukuluku ma sin Esin rẹ gẹge bi Olorun ba ti ran. Ẹnyin ọ ki ibi ipara kiyesi ogun, ti Baba ati Iya yio bi ọmọ tan, ti ọmọ na ko ni ṣe ti awọn Oba re, Baba ati Iya le ṣe Imọle ki ọmọ ya si esin kiristẹni, tabi ki awa se fun ọmọ yen pe esin to ya si yen ko nse esin to dara, mo fẹ mọ idi eyi pẹlu Alaye.

Mo iṣ ki e si fun mi, enyin Alfa Musulumi ti ẹ ti mọ ọrọ ti dara ati eyiti ko dara yio. Tani o nṣe ti Olọrun nipa awa mọ ? mo fẹ mọ, ati ohun ti o ri ko to ṣe bẹ, iyoku di ọsẹ ti o mbọ lagbara Oluwa.

---

# Olopa W'ewon Osu Mefa

KANO — Oga Ọlọpa kan ti o nṣiṣẹ ni'le iṣẹ Eleto ile ilu okeere (Immigration Office) nilu Kano ni nwọn fi sun ẹwọn wipe o fi owo pamọn kan fun oga rẹ ni owo-ẹbun (bribe) niwaju adajọ ilu Kano.

Awọn Ọlọpa sọ wipe oga ọlọpa na fi owo pọnun kan fun ọmọ ọga rẹ wipe ki o fi fun baba rẹ ti o nṣe iwadi iwa ọjẹju kan ti o hu nibi iṣẹ.

Nitorina ti nwọn ro ẹjọ na, adajọ da lẹbi o si ju s'ẹwọn oṣu mẹfa.

---

# Asoju ilu Belgium yo ti ilu re kuro

Eko— Asoju ilu Belgium ni ilẹ Nigeria, ọgbọn Mons. H. Beduwa, so wipe ni oruko ijoba on, ijoba Belgium tabi enikeni ti o je ara ilu Belgium ko lowo ninu mimu awon mu Ogbeni Lumumba losi ilu Katanga.

Ijoba ilu Belgium ko si ni imo nipa aye ti o wa.

Ijoba on si lodi si iwakuwa yowu ti nwon le hu si Ogbeni Lumumba.

Nipati enia gbigba fun omo ogun Katanga, Ijoba o nti ninu wipe bi nwon ba fi ehuro iru e yi pere, ijoba yio se iwadi lati se eto fun.

**HINDU SANKARA'S**
**Religious Art Jewelleries**



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, Kawachas, Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

Enclose 4/- British Postal Order by airmail for catalogues and literature.
HINDU SANKARA, 421 Archway Road, London, N.6, England



ARADAN NARVIGORA

Oogun yi je pataki fun Imọrile agba ti ureno ... Owo ... "Alesa ... 5/5 ... 1/6 e.g. 7/ Post Free.

THE EGBA TRADING ARADAN STORES
112, Denton Street, 18, Denton Bridge Street
P. O. Box 2 Ebute-Metta.

Phone : 44153. A lua wa ni New Motor Park (Ogunpa), Ibadan

# OWO KO SE FI SERE

(Lati ọwọ Adeniran)

(O Bẹrẹ Loju Ewe Keji)

ITUMỌ ITAN MI NI YI

Ni ojo kan Baba kan ni ọmọ mẹta, nigbati wọn dagba tan Baba [illegible] wipe ẹnyin ọmọ mi o, kini ẹ fẹ ṣe o? Ekini dahun wipe on yio ma yọna kiri ni toun, ekeji ni o n yio ma ṣe ẹru ọba ni, ẹkẹta dahun, o ni on yio ma pa itan kakiri ni toun ni.

Baba wọn ni ki ọkọkalukọ ma lọ sesu iṣẹ rẹ o. Eyi akọbi yen gbe ada, o bẹrẹ si ṣe ọna kiri gbogbo ọna oko. Ekeji lọ si ilu kan ti irin ibẹ to ọdun mẹwa si ilu wọn o nlọ ṣe ẹru Oba ibẹ. Ẹkẹta bẹrẹ si pa itan kiri ati awọn owe nla-la loun re.

Nigbati o [illegible] gbọ wipe ilu pipa ta ni ilu kan ti a npe ni "Aiye Ilu Ọfọ ada" ni o ba gbera odi ilu yi, bi o ti nlọ o ba ẹgbọn re loun ti o nyẹ ọna lọ, o ki, o ni mo fẹ lọ ilu "Aiye ilu l'ọofa loni" lọ pa itan nibẹ, ẹgbọn re [illegible] lọ o. O ba ẹgbọn ko gbọ, o nlọ.

Nigbati ode ilu yi, o lọ si ọdọ ọba o ni on "Apa Alọ ta" nigbati o ma wo ẹhin Ọba, ẹgbọn re l'o ri, ẹgbọn rẹ si [illegible] i fun pe ile yi buru pupọ o jọwọ ma ṣe pa alọ nibi yi o.

Ko gba, Ọba ni ṣe o le mọ itumọ awọn alọ mẹta kan kekeke, o ni Kabiyesi, ọba, emi a mọ, ẹ pa fun mi ki ngbọ. Ọba si tun wi fun pe ti o ko ba mọ ngo pa ọ ni o. O si dahun o ni emi yio mọ o. Nigbana ni eru Oba kan bo s'ode o ni "Ara Alọ ta" ka oye irun ori mi ki o si sọ iye re fun ọba Apalọ ta si tu irun ori ẹru na ni ikọkan, ṣugbọn bi o ti nṣe ni ẹru Ọba nke ye, ye, yee, nigbati o ya ẹru ọba sa kuro niwaju ọba.

Apalọ ta si dahun o ni Kabiyesi, Oba eru nyin sa kuro niwaju mi, Ọba si rẹrin ati awọn ẹmẹwa re pẹlu.

Nigbana ni ọba ni amoye eniyan ni o, ati pẹlo si gbọn pupọ Ọba ni ki won fun ni owo, aṣọ, eru ati gbogbo nkan ini eniyan. Ọba wa tun fun ni oja mẹta pelu gẹgẹ bi aṣa ile won.

Apalọta wa pe ẹgbọn re ni won ba mbọ wa si ilu wọn, bi wọn ti mbọ, wọn ba ẹkẹta wọn ti o nyẹ ọna bọ, ni wọn ba rohin fun ni wọn ba ni ki o kalọ.

(Iyoku di ọsẹ to mbọ)

## Idajo Ejo Igbimo Ilesha Digbamiran

Ibadan – Ninu Kotu giga ti ilu Ibadan ni nwọn ti pari iro ati gbigbo ejo ti awọn igbimo ibilẹ ilu Ilesha pe Gomina ati alaṣẹ ijọba ibilẹ Iwo-Orun l'oruko Ọgbẹni Michael Ekundare, ti o jẹ "Ab'[illegible]" (Chief Whip) ninu igbimọ [illegible] lori tita ka ti ijọba ipinlẹ Iwo-Orun ti igbimo na [illegible] ti nwọn ṣe fi pinnu wipe ki Alayeluwa Ogunmokun, Biladu Kẹta, Ọba Owa Ilesha fi oye re ọba re silẹ."

Nwọn ti bẹrẹ si ro ejọ na lati ibẹrẹ ọsẹ iyi pẹlu awọn ogbogi ninu ofin, agbẹjẹro, Oloye Rotimi Williams Q. C. wa fun ijọba Iwọ-Orun pẹlu amofin ijọba, ati Sir Frank Soskice, QC. wa fun igbimọ ibilẹ Ilesha ati Ọgbẹni Olowofoyeku.

Adajọ ko sọ asiko ti yio ṣe idajo ejọ na, o kan sọ wipe dajo di igbam ran ni.

KELVINATOR REFRIGERATORS

The Ideal Choice

For the Modern Kitchen



CAPACITY
4.6 cu. ft.
6 cu. ft.
7.7 cu. ft.
9.4 cu. ft.
12.8 cu. ft.
H. P. TERMS AVAILABLE

Distributed by

LEVENTIS

TECHNICAL

Available at

LEVENTIS Marina — Iddo — Ibadan — Kano — Port Harcourt — Aba

and leading Department Stores

## AWON ODUN ILU NASARETI

Gẹgẹ bi ati bẹrẹ si ni oye nipa igbesi aiye Jesu. Ako le ṣe alairanti ibi ti o ti bẹrẹ. Ibẹ na ni ilu kekere kan wa ninu ẹya ilu Galili ti a npe ni Nasarẹti.

Nigbati Josẹfu ati aya rẹ Maria npada bọ lati ile Egypt, ero ọkan wọn ni lati joko ni Judia, ṣugbọn nigbati wọn de tosi, wọn ri pe Akẹlọ, eni buburu ọmọba Ẹrọdu, ni o jọba dipo baba rẹ lori ilu Judia. Wọn tun bẹrẹ irin ajo wọn si apa ilẹ Gusu lọ si ilu Nasarẹti. Irufẹ ọna bayi ni Galili fi di ibugbe tabi ile fun Jesu Oluwa wa. Galili si yatọ pupọ si Judia.

(Iyoku di ọsẹ to mbọ)

## Ogun Iwosan Ajebidan

Lati Ọwọ Onisegun Eleti-Ọfẹ

OGUN INARUN

Egbo Ipẹtẹ, Ẹra, Aidan Iyọ oyinbo, Ata, Iyọ, Alubosa elewe, [illegible] mimuk niwọn idaji ṣibi kọkan fun ọkọ-taya

Printed & Published By The Union Printing and Publishing Company, 15, Kosoko Street P. O. Box 467 Lagos Phone 23373